# IRIBỌMI ATI IDANWO JESU
## Matteu 3:13-17; 4:1-11; Luku 4:14-32
## ẸKỌ 17 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹ kọ oju ija si Èṣu, on ó si sá kuro lọdọ nyin" (Jakọbu 4:7).**

### Ọdọ - Agutan Ọlọrun

"Wò o, Ọdọ-agutan Ọlọrun, ẹniti o kó ẹ̀ṣẹ aiye lọ!" (Johannu 1:29) Pẹlu awọn ọ̀rọ aikú wọnni ni Johannu fi ṣi ọna Kristi silẹ fun iṣẹ-iranṣẹ Rẹ̀ eyi ti o mu igba oore-ọfẹ wọle.

Ogunlọgọ awọn eniyan ti pejọ pọ lati gbọ iwaasu Johannu, o si ti ṣe iribọmi fun ọpọlọpọ awọn ti o ti yi pada ninu Odo Jọrdani. Ni ọjọ kan o ṣakiyesi ẹni ajeji kan laaarin ọpọ ero. Jesu n bọ wa ṣe iribọmi! Bawo ni ọkàn Johannu ti yọ̀ to bi o ti da Ọmọ Ọlọrun mọ̀ yatọ! Johannu ti waasu fun awọn eniyan naa pe Ẹni kan ti O pọ ju oun lọ n bọ wá -- O si ti de nisinsinyi!

Johannu ro pe oun kò yẹ lati ṣe iribọmi fun Jesu, ṣugbọn nipa aṣẹ Rẹ̀ awọn mejeeji rin wọ inu odo lọ "lati mu gbogbo ododo ṣẹ." Nigba gbogbo ni Johannu maa n gbọran si Kristi lẹnu nitori ti o mọ̀ pe Ọmọ Ọlọrun ni Oun I ṣe. Bi a ti n kọ ẹ̀kọ́ yii, a oo kọ́ bi Ọlọrun ti fi otitọ yii han fun Johannu.

Johannu ṣe iribọmi fun Jesu gẹgẹ bi o ti ṣe fun awọn ẹlomiran pẹlu. Ṣugbọn nigba ti Jesu jade ninu omi, nnkankan ṣẹlẹ eyi ti kò ṣẹlẹ ri. Ẹmi Ọlọrun sọkalẹ sori Rẹ̀ ni ìrí adaba, a si gbọ Ohun kan lati Ọrun wi pe, "Eyí ni ayanfẹ ọmọ mi, ẹniti inu mi dùn si gidigidi" (Matteu 3:17). Iwọ le ro pe gbogbo eniyan yoo gba Jesu gbọ́ nigba ti wọn gbọ́ ohùn Ọlọrun ti wọn si ri adaba naa; ṣugbọn ki i ṣe gbogbo wọn ni o ni ọkàn otitọ.

Johannu jẹ wolii, Ọlọrun si ti sọ fun un pe Ẹni ti o ba ri ti Ẹmi ba sọkalẹ sori Rẹ̀ ti O si bà le E, Oun naa ni Messia. Johannu ati awọn ọmọ-ẹyin rẹ wa nibẹ nigba ti o ṣẹlẹ; wọn rii, wọn si gbagbọ́. Johannu wi pe, "Emi si ti ri, emi si ti njẹri pe, Eyi li Ọmọ Ọlọrun" (Johannu 1:34).

#### Mẹtalọkan Mimọ́

A le fi oju inu wo aworan alarinrin nipa Mẹtalọkan ninu ẹ̀kọ́ yii -- awọn Ẹni Mẹta ninu Iwa-Ọlọrun. Ọlọrun Baba sọ̀rọ lati Ọrun si Ọlọrun Ọmọ ti n jade wá lati inu omi, nigba ti Ọlọrun Ẹmi Mimọ́ bà le Jesu ni iri adaba. Lẹyin eyi, Jesu pe Ẹmi Mimọ́ ni Olutunu, O si ṣeleri pe nigba ti Oun ba lọ Olutunu yoo wá lati maa ba wọn gbé. Jesu tun pe Ẹmi Mimọ́ ni Ẹmi Otitọ nì ti yoo tọ́ awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ti yoo si ṣamọna wọn sinu otitọ gbogbo.

Ẹmi jẹ oniwa-tutu bi adaba. Kò ni wa sinu ọkan ti kò mọ́. Ṣugbọn ti a ba ti wẹ̀ wa ninu Ẹjẹ Jesu, awa naa le gba A. Nigba ti O ba wọle a o kún fun ifẹ ati ayọ nla ati gbogbo nnkan ti n gbe inu ọkan Jesu. Ẹmi Mimọ́ jẹ Ẹni kan O si jẹ ọkan pẹlu Jesu. Kiki inu ọkan ti Jesu ba wà ni Oun n gbé.

### Idanwo Ogoji Ọjọ

Bi o tilẹ jẹ pe Ẹmi ti bà le Jesu, Oun kò i tii ṣetan lati bẹrẹ iṣẹ-iranṣẹ Rẹ̀. Igba iyiriwo n bọ niwaju Rẹ̀. "Nitori niwọnbi on tikararẹ̀ ti jiya nipa idanwo, o le ràn awọn ti a ndan wo lọwọ" (Heberu 2:18).

Ẹnikẹni ti o ba fẹ ṣiṣẹ fun Ọlọrun ni lati là akoko idanwo kọja. Ọlọrun n fẹ yiiri wa wò lati ri i boya a fẹ ṣe ohun ti a wi, tabi bẹẹ kọ, nigba ti a sọ fun Un pe a oo "rin gbogbo ọna naa já" ao si ṣe ohunkohun ti O ba fẹ ki a ṣe.

Ẹmi dari Kristi sinu iju nibi ti O wà fun ogoji ọjọ, Oun nikan pẹlu awọn ẹranko ẹhànna lai ni ohun kan lati jẹ. Ni tootọ ebi pa A lẹyin aawẹ gígùn naa, Satani si rò pe: Anfaani mi ni yii. Ni akoko yii ailera Oluwa ni ebi Rẹ̀, nitori naa èṣu wi fun Un pe bi Oun ba i ṣe Ọmọ Ọlọrun nitootọ ki O sọ okuta di akara ki O ba le jẹ. Iba rọrùn fun Jesu lati sọ okuta di akara, nitori Jesu le ṣe ohun gbogbo. Ṣugbọn Oun kò ni ifẹ rara lati gbọ́ ti oludanwo Rẹ̀.

### Idà Ẹmi -- Ọrọ Ọlọrun

Oluwa fi han wa bi a oo ti ṣe kọju ija si èṣu. Nigba ti Satani n fẹ ki O ṣe akara, Kristi sọ Iwe Mimọ́ fun un. Ni ọpọlọpọ ọdun ṣiwaju, Mose ti wi fun awon Ọmọ Israẹli pe, "enia kò ti ipa onjẹ nikan wà lãye, bikoṣe nipa gbogbo ọ̀rọ ti o ti ẹnu OLUWA jade" (Deuteronomi 8:3). Bi a ba mọ Iwe Mimọ́ a le dá ọta lohun bakan naa nigba ti o ba mu idanwo wá. O ṣe danindanin fun wa lati kọ́ Bibeli ki a si mọ awọn ileri ti Ọlọrun ti ṣe fun wa.

Satani kò titori pe oun sọ ogun kan nù pẹlu Jesu ki o ṣiwọ. O gbé E lọ si ṣonṣo Tẹmpili ni Jerusalẹmu o si wi fun Un pe ki o bẹ silẹ lati ibi giga naa. O wi pe, bi Jesu ba i ṣe Ọmọ Ọlorun ni tootọ, Baba Rẹ̀ kò ni jẹ́ ki O fara pa. O mọ̀ wi pe Dafidi ti sọtẹlẹ nipa Jesu pe awọn angẹli yoo gbe E soke ki O má ba fi ẹsẹ Rẹ̀ gbún okuta (Orin

Dafidi 91:12). Jesu naa mọ̀ ẹsẹ Iwe Mimọ́ yii; ṣugbọn O mọ̀ ju bẹẹ lọ. O tun fi ọrọ da a lohun pe: “Iwọ kò gbọdọ dán Oluwa Ọlọrun rẹ wò.”

Sibẹ Satani kò jẹ fi Jesu silẹ. Titi a oo fi fi ayé silẹ, ọta ẹmi kò ni ṣiwọ gbigbiyanju lati yi iṣisẹ wa pada ni titẹle Oluwa. Ṣugbọn a dán Jesu wo ni gbogbo ọna bi awa, O si ti pinnu lati ran wa lọwọ lati bori gbogbo idanwo bi a ba wò O fun iranwọ.

Satani mu Jesu lọ sori oke giga-giga nibi ti wọn ti le ri gbogbo ilẹ ọba aye. Eṣu mọ pe ọpọlọpọ eniyan le ta ẹmi wọn ki wọn le jẹ ọlọrọ ati alagbara, o si fẹ mọ boya Jesu yoo ṣe bẹẹ. Ṣugbọn akoko kò i tii to fun Jesu lati ṣakoso ijọba nipa ti ara lori aye – ati ju bẹẹ lọ, nigba ti o ba tó akoko, Ọlọrun, kii sii ṣe Satani, ni yoo fi agbara fun Un.

Eṣu gbojú-gboya lati wi pe ki Jesu wolẹ ki O si foribalẹ fun oun. A kò ri bi ẹnikẹni ti ṣe le fẹ lati foribalẹ fun eṣu; ṣugbọn ọpọlọpọ eniyan ni ilẹ okeere, ati ni ilẹ ti wa paapaa, ni wọn n foribalẹ fun awọn ẹmi eṣu ti wọn si n kọ tẹmpili fun wọn. Nigba miiran wọn a tilẹ maa fi ọmọ wọn rubọ fun eṣu. Ṣugbọn Jesu wi pe, “Oluwa Ọlọrun rẹ ni ki iwọ ki o foribalẹ fun, on nikanṣoṣo ni ki iwọ mã sin.”

**Aṣẹgun**

Lẹyin gbogbo idanwo wọnni o rẹ̀ Jesu pupọ -- ṣugbọn O ti bori. Ọlọrun sọ nigba ti a ṣe iribọmi fun Jesu pe inu Oun dùn si Ọmọ Oun, ṣugbọn inu Rẹ̀ yoo ti dùn pupọ si I tó nisinsinyi nigba ti O ri i ti Olugbala wa ni iṣẹgun nlánlà lori ọta. O ran angẹli lati ṣe iranṣẹ fun Un ati lati fun Un lokun. Inu Oluwa maa n dùn si awọn ọmọ Rẹ̀ pẹlu nigba ti wọn ba ṣẹgun oludanwo, Oun a si maa fun wọn ni ibukun alarinrin fun ère.

**AWỌN IBEERE**

1. Njẹ Johannu rò pe oun yẹ lati ṣe iribọmi fun Kristi?
2. Njẹ iwọ ro pe Johannu ti ri Jesu tẹlẹ ki O to wá fun iribọmi?
3. Ta ni Ẹni naa ti O bà sori Jesu ni iri adaba?
4. Njẹ iwọ ro pe Jesu le sọ okuta di akara?
5. Nigba ti Jesu wi pe, “Pada kuro lẹhin mi, Satani …” a kà pe “Èṣu fi i silẹ lọ.” Ẹkọ wo ni eyi kọ́ wa?
6. Ki ni n ṣẹlẹ nigbakuugba ti eniyan ba tẹle aṣẹ Satani?